# JERUSALẸMU TITUN

## Ifihan 21:1-27

## ẸKỌ 466 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ohun alaimọ́ kan ki yio si wọ̀ inu rẹ̀ rara, tabi ohun ti nṣiṣẹ irira ati eke; bikoṣe awọn ti a kọ sinu iwe ìye Ọdọ-Agutan" (Ifihan 21:27).**

**I Ohun Gbogbo di Titun**

1. Johannu rí Ọrun Titun, aye Titun, ati Jerusalẹmu Titun, Ifihan 21:1, 2; Isaiah 65:17; 66:22; Johannu 14:2, 3; 2 Peteru 3:13
2. Johannu gbọ́ Ohùn kan lati Ọrun ti n sọrọ nipa ibukun ti o wà ninu ki Ọlọrun maa bá awọn eniyan gbé, Ifihan 21:3, 4; 7:15-17
3. Onidajọ lori Itẹ́ na ọwọ́ ipe ologo jade fun ìye ainipẹkun; ṣugbọn fun awon ti o kọ̀, igbẹyin wọn ni ikú keji, Ifihan 21:5-8; 20:14, 15; 22:17

**II Apejuwe Jerusalẹmu Titun**

1. Angẹli kan mú Johannu lọ ninu Ẹmi lati ri Jerusalẹmu Titun naa kedere, Ifihan 21:9, 10;Heberu 11:10, 16; 13:14
2. Ilu naa ti Ọrun sọkalẹ; a sọ ìrí ati titobi rẹ̀ yika, Ifihan 21:10-18
3. A fi okuta iyebiye ṣe ipilẹ ogiri ilu naa lọṣọ, ẹnubode rẹ̀ si jẹ́ perli, Ifihan 21:19-21
4. Ọlọrun ati Ọdọ-Agutan ni Tẹmpili ati Imọlẹ̀ ilu naa, Ifihan 21:22, 23; Isaiah 60:19, 20
5. Kìki awọn ti o ni igbala ni yoo gbadun awọn ibukun ilu mimọ́ naa, Ifihan 21:24-27

## ALAYE

**Ọrun Titun ati Ayé Titun**

A ti kọ́ nipa Itẹ́ nla Funfun ati Ẹni ti o joko lori rẹ̀ niwaju ẹni ti ayé ati ọrun fò lọ. Fun gbogbo ẹlẹṣẹ ti o ti gbé ori ilẹ ti a kò rà pada, idalẹbi ni ọ̀rọ ẹjọ wọn, iyà wọn ni ikú keji, a si gbé wọn sọ sinu adagun iná. Ṣugbọn wo bi eyi ti yatọ to si ti awọn ti a ti gbala! Wọn foju ri igbekalẹ Ọrun titun ati ayé titun eyi ti o logo to bẹẹ ti o fi kọja ahọn ọmọ-eniyan lati ṣapejuwe rẹ̀ patapata tabi eyi ti ọmọ-eniyan le fi ero ori mọ̀.

Ni atetekọṣe Ọlọrun sọkalẹ O si rìn O si sọrọ pẹlu eniyan, ẹda ọwọ́ Rẹ̀. Nisisiyii Johannu gbọ́ Ohùn nla kan lati Ọrun wá ti n wi pe eyi ni yoo tun jẹ́ ipo ibukun ninu iṣẹda titun naa, nitori Ọlọrun funra Rẹ̀ ni yoo wá bá awọn ti Rẹ̀ gbé ninu irẹpọ didùn ati idapọ ti o ni ibukun. "Ifẹ tirẹ ni ki a ṣe, bi ti ọrun, bẹ̃ni li aiye" ni a o muṣẹ ni tootọ.

Nigba naa ni Apọsteli Johannu gbọ́ Ẹni ti o joko lori Itẹ́ ti O n sọ ti O si n fi idi rẹ̀ mulẹ pe ohun gbogbo yoo di ọtun. O wi pe Oun ni ipilẹṣẹ ati opin, Alfa ati Omega. Lẹyin naa, iyanu ninu iyanu, Ẹni Mimọ yii rán ipe ti o larinrin ti o si ni ogo jade si gbogbo ẹni ti n gbé ori ilẹ̀: "Emi ó si fi omi fun ẹniti ongbẹ ngbẹ lati orisun omi ìye lọfẹ." Orisun naa ṣi silẹ lonii. Omi Iye naa n ṣàn sibẹ, ati "Ẹniti o ba ṣẹgun ni yio jogún nkan wọnyi; emi o si mã jẹ Ọlọrun rẹ̀, on o si mã jẹ ọmọ mi." Ipè ti o ni ibukun si Ọrun titun ati ayé titun ṣi silẹ. Amuyẹ kan ṣoṣo ti o gbà ni pe ki a poungbẹ ni tootọ fun awọn nnkan ti ẹmi ti n ti Ọrun wá. Pẹlu ipè yii ni ikede idakeji – adagun ti n fi iná ati sulfuru jó, eyi ti i ṣe iku keji. Ninu ẹgbẹ́ yii ni awọn apaniyan, agbere, oṣó, ati awọn abọriṣa; ṣugbọn awọn nikan kọ́ -- o tun sọ pe awọn ojo ati awọn alaigbagbọ́, awọn eke gbogbo pẹlu awọn ẹgbẹ yii.

**Jerusalẹmu Titun**

Ninu ẹsẹ keji ori ẹkọ wa, Johannu sọrọ, ki i ṣe pe oun ri Ọrun titun ati ayé titun nikan, ṣugbọn ilu titun -- Jerusalẹmu mimọ́ -- ti n ti ọdọ Ọlọrun sọkalẹ lati Ọrun wá. Apejuwe rẹ̀ ni pe ilu naa ni a ti "mura silẹ bi iyawo ti a ṣe lọṣọ́ fun ọkọ rẹ̀." Angẹli kan mu Johannu lọ ninu ẹmi si òke nla kan ti o si ga, o si fi ìrí ti o ṣe kedere si i hàn án nipa ilu ologo yii o si pè e ni "iyawo, aya Ọdọ-Agutan." Ilu ọrun yii ni iyawo Kristi, ki i ṣe ile nlá nlá tabi oju-ọna gbigbooro ni o mu un jẹ ilu bi ko ṣe nitori awọn ti a ti sọ di mimọ́ ti a si ti ṣe logo ti n gbé inu ilu naa. Awọn ile nlá nlá ati ọpọlọpọ ọ̀na ti o gbooro nikan kọ́ ni o n ṣe ilu nla. Ko le si ilu alaaye lai si awọn eniyan lati gbé inu rẹ̀, iwọ ko si le ni ilu lai si awọn ile nlá nlá ati opópo ti a ṣẹto rẹ̀ ni ọna ti yoo fi jẹ́ irọrun fun awọn olugbe inu rẹ̀.

Awọn ti wọn gbé igbesi-ayé igbagbọ́ lati ayeraye ti n fojusọna fun ilu yii. A kà nipa ti Abrahamu, "Nitoriti o nreti ilu ti o ni ipilẹ̀; eyiti Ọlọrun tẹ̀do ti o si kọ́" (Heberu 11:10). Ati nipa ti awọn eniyan mimọ́ ìgba nì a kà

pe: “Ṣugbọn nisisiyi nwọn nfẹ ilu kan ti o dara jù bẹ̃ lọ, eyini ni ti ọ̀run: nitorina oju wọn kò ti Ọlọrun, pe ki a mã pe On ni Ọlọrun wọn; nitoriti o ti pèse ilu kan silẹ fun wọn” (Heberu 11:16). Apọsteli naa n ṣe ẹnu fun gbogbo awọn Onigbagbọ́ akoko ti rẹ nipa ọ̀rọ ti o n sọ o ni “Awa kò ni ilu ti o wà titi nihin, ṣugbọn awa nwá eyiti mbọ̀” (Heberu 13:14). Laiṣiyemeji, nipa ilu yii ni Jesu funra Rẹ̀ n sọ ninu ori kẹrinla Johannu:

**“Ninu ile Baba mi ọ̀pọlọpọ ibugbe li o wà: … emi nlọ ipèse àye silẹ fun nyin.**

**“Bi mo ba si lọ ìpese àye silẹ fun nyin, emi o tún pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu.”**

Ni tootọ n jẹ eyi kò n dún bi igba ti Ẹni ti yoo ṣe Ọkọ ba n ba ẹni ti yoo ṣe Iyawo sọrọ ileri Rẹ̀?

Johannu sọ wi pe oun ri ilu yii “nti ọrun sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun wá.” Ọrun ni ibẹrẹ rẹ̀. Eso agbara ati ọgbọ́n Olodumare ni eyi i ṣe gan an. Ẹni ti o dá awọn ayé ni Ẹlẹda ilu yii. Eniyan, ẹni-kikú kò lọwọ ninu kikọ́ ilu yii. Kò ni ọga ile kikọ tabi awọn oṣiṣẹ ile kikọ́ bi ko ṣe Ọlọrun funra Rẹ̀. Ogo ati ẹwa ilu yii ṣoro lati ṣe apejuwe tabi lati fi oju inu wò; lati inu rẹ̀ ni ogo Ọlọrun ti n tàn jade. Johannu sọrọ rẹ̀ pe okuta ti o ṣe iyebiye pupọ ni a fi ṣe e, okuta jasperi, ti o mọ́ bi kristali. Okuta jasperi ni orisirisi àwọ oṣumare lara, ṣugbọn imọlẹ̀ kò le kọja ninu rẹ̀. Ilu yii ni ìrí jasperi ṣugbọn imọlẹ̀ le kọja ninu rẹ̀. O dabi diamọndi iyebiye, ti o mọ́ bi kristali, o mọlẹ gaara.

O ni “odi nla ati giga” eyi ti a fi jasperi kọ́, odi naa si duro lori ipilẹ okuta mejila, ọkọọkan dá wà o si jẹ́ ọṣọ ti o yanju. Awọn nnkan kan wà ninu ayé ti a maa n ri ni iwọn kinun ti wọn si ṣọwọn, ti wọn si lẹwà ti wọn si maa n wà titi to bẹẹ ti a fi n pè wọn ni okuta iyebiye. Oriṣi mejila ninu okuta wọnyii ni i ṣe ipilẹ lori eyi ti a kọ́ awọn odi jasperi ati ilu naa funra rẹ̀. Lara odi yii ni aafo mejila wà pẹlu ẹnubode mejila; ọkọọkan ẹnubode naa ni a fi odidi perli kan ṣe.

Awọn eniyan ti kọ́ ilu ti o gbayì pupọ, ile eyi ti wọn ti fi oriṣiriṣi okuta iyebiye ati irin kọ́, ti a si ti ṣe lọṣọ ti a si ti mu ki o dán dé àye ti o ga: ṣugbọn pẹlu gbogbo eyi wọn dabi asán ti a ba fi wọn wé ilu yii. Ibi kan wà ninu olukuluku ilu ti ayé yii eyi ti o tẹ́ awọn eniyan lọrùn lati fi ohun ti kò ni ọlá to bẹẹ ṣe, ibi ti olukuluku eniyan n tẹ̀ mọlẹ̀ labẹ ẹsẹ rẹ̀. Ṣugbọn eyi fi bẹẹ gbé iyi ilu ọrun yii ga lọpọlọpọ pe kiki wura pipe ni ita rẹ̀ paapaa. Ni tootọ wura naa peye to bẹẹ gẹẹ ti ko si le ni ẹgbẹ́ bi o ti wu ki iṣẹ ọna ti a ṣe si wọn lara ti pọ̀ tabi dara to, wura ti o ni àbami ẹwa ọrun – o mọ́ bi kristali ti o mọ́ ju lọ.

Titobi ilu ologo yii, pẹlu titobi kikọ́ rẹ̀, mi ironu ọmọ-eniyan ni tootọ. Lati inú iriri awọn ti o ni oye jù lọ nipa bi a ti n wọn nnkan ni igba laelae, ibusọ wa kan jẹ́ furlọng mẹjọ. Iṣiro yii yoo fi ye ni pe ririn ilu naa já yoo jẹ́ ẹẹdẹgbẹjọ (1,500) mile ni iha gbogbo. Woye ilu ti yoo nà lati opin ilẹ Canada titi de opin ilẹ Mexico; lati eti Okun Pacific titi fẹrẹ de Odò Mississippi. Ṣugbọn ko i ti tán: a sọ fun ni pe “gigùn rẹ̀ ati ibú rẹ̀ ati giga rẹ̀ si dọgba.” O fẹrẹ daju pé ni Ilu Mimọ́ ti Johannu ri yii n ṣe ni a kọ́ títì soke títì, pẹtẹsi soke pẹtẹsi loke lọhun lọhun, titi giga naa fi to ẹẹdẹgbẹjọ (1,500) mile. Eyi ni ilu ti o ni “ọ̀pọlọpọ ibugbe” ti a ti ṣeleri rẹ̀.

Ninu ilu yii kò ni si ọgbà alaisan, nitori ti ki yoo si “ọfọ, tabi ẹkún, bẹ̃ni ki yio si irora mọ́.” Kò ni si ibi isinkú, nitori “ki yio si si ikú mọ́” ninu odi rẹ̀. Ọgba ọlọ́pa, ọgbà ẹ̀wọn ati ile ọmọ alaigbọran kò ni si ninu nnkan ti a kọ́ si ilu yii, nitori “ohun alaimọ́ kan ki yio si wọ̀ inu rẹ̀ rara, tabi ohun ti nṣiṣẹ irira ati eke.”

Bi awari ọgbọ́n iná manamana (electricity) ti jẹ́ iyanu to, ni ilu àra yii a kò ni fẹ́ fitila rara – ki tilẹ ṣe imọlẹ̀ oorun tabi ti oṣupa, nitori a sọ fun ni pé “ogo Ọlọrun li o ntàn imọlẹ si i, Ọdọ-Agutan si ni fitila rẹ̀.” Ninu ilu yii Johannu kò ri tẹmpili kankan. Eyi ki i ṣe nitori ijọsin dopin tabi pe idapọ pẹlu Ọlọrun kò tun ni si mọ́. Niwọn bi Ọlọrun ti wà laaye, ifẹ ati iyin si I kò le dakẹ, bẹẹ ni iṣẹ-isin kò le duro. Kaka bẹẹ; Ọlọrun funra Rẹ̀ ati Ọdọ-Agutan ni i ṣe Tẹmpili ilu yii. Awọn olujọsin nibẹ ni idapọ taara pẹlu Ọlọrun ninu ifarahan ogo Rẹ̀ ti o bò wọn mọlẹ̀ ati gbogbo ilu wọn yika bakan naa. Bi alufa ti a ti yà sọtọ wọn o ti wọ Ibi Mimọ Julọ nigba naa, ninu ikuuku ogo Ọlọrun gan an ti n rọ̀dẹ̀dẹ̀. A! iru akoko ologo wo ni yii ti n duro de awọn ti a kọwe orukọ wọn sinu Iwe Iye ti Ọdọ-Agutan!

**“Oluwa, opin ajo ti oju mi nnọga si,**

**Maa wà loju ọkàn mi titi ilẹ o fi mọ́,**

**Jẹ k’apa gbagbọ ati ifẹ rù mi d’oke layọ**

**Titi ade iṣẹgun o fi d’ori mi.”**

**AWỌN IBEERE**

1. Sọ ni ṣoki bi awọn ọrun titun, ayé titun, ati Jerusalẹmu Titun yoo ti ni ibukun to.
2. Ki ni ṣe ti Johannu fi lo ède “iyawo” ni ṣiṣapejuwe Jerusalẹmu Titun?
3. Bawo ni ilu naa ti tobi to?
4. Ṣapejuwe kikọ ilu naa.
5. Awọn wo ni olugbe ilu yii?
6. Ipese wo ni a ṣe silẹ fun ẹsin ni Ilu Mimọ yii?